# ONIGBAGBỌ AJAGUN ATI IHAMỌRA RẸ̀

**Efesu 6:10-24**

**ẸKỌ 404 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ki iṣe ẹ̀jẹ ati ẹran-ara li awa mba jijakadi, ṣugbọn awọn ijoye, awọn ọlọla, awọn alaṣẹ ibi òkunkun aiye yi, ati awọn ẹmi buburu ni oju ọrun" (Efesu 6:12).**

**I Eredi Nini Ihamọra ti Ẹmi**

1 Agbara ati ipá ọmọ-ogun Onigbagbọ́ wà ninu Oluwa, Efesu 6:10.

2 Paulu fi yé ni eredi rẹ̀ ti a ṣe ni lati gbé gbogbo ihamọra wọ̀ nitori agbara ọ̀tá, Efesu 6:11, 12

**II Igbani-niyanju lati Gbé gbogbo Ihamọra Ọlọrun Wọ̀**

1 Ihamọra yii yoo ran ni lọwọ lati lè kọju ija si idanwo ati lati lè duro, Efesu 6:13,

2 Ihamọra Ọlọrun jẹ́ aabo nipa ti ẹmi lati ori dé ẹsẹ, Efesu 6:14-17; 2 Kọrinti 10:4, 5; 1 Tẹsalonika 5:8; Isaiah 11:5; 59:17

**III A Paṣẹ fun Wa lati Gbadura**

1 Adura ni lati jẹ igba gbogbo ati ninu Ẹmi, Efesu 6:18

2 Paulu beere fun iranwọ adura ki oun le fi igboya waasu Ihinrere, Efesu 6:19, 20; Kolosse 4:3, 4

3 A rán Tikiku si Efesu lati royin ati lati tù wọn ninu, Efesu 6:21, 22

4 Paulu gbadura o si beere ibukun si ori awọn ara Efesu, Efesu 6:23, 24

## ALAYE

### Ihamọra ti A Gbọdọ Ní

Paulu Apọsteli mọ̀ dajudaju pe gbogbo ọmọ-ogun Onigbagbọ gbọdọ ni ihamọra kikún. Iriri ti rẹ̀ ti fi hàn pe ogun wà dajudaju ati pe ọta yoo ṣe ohun gbogbo ti o wà ni agbara rẹ̀ lati wó odi Onigbagbọ́. Lati ni ihamọra ki i ṣe fun aabo nikan, ṣugbọn a ni i lò lati jade lọ sinu ayé lati lọ waasu Ihinrere. Paulu ti kọ́ awọn ara Efesu wọnyii nipa iwa wọn si ara wọn. O ti kọ́ ọkọ ati aya; oniṣẹ ati oṣiṣẹ; awọn ọmọ ati awọn obi; nisisiyii o wá n sọ fun wọn pe lati pa ẹ̀kọ wọnyii mọ́, ati lati le jẹ ere gbogbo anfaani ti Ọlọrun ti ṣe ileri fun wọn, wọn ni lati ni gbogbo ihamọra Ọlọrun.

O sọ ọ gbangba pe a gbọdọ gbé ihamọra yii wọ̀. Igbẹkẹle wa ni ti pe ihamọra yii wà ko tó. O le ye wa bayii pe bi o tilẹ jẹ pe ile ihamọra ija kun fun oriṣiriṣi ohun ija, sibẹ eyi kò ṣe anfaani ti o tọ́, ti o si yẹ titi di igba ti awọn ohun ija naa ba bọ́ si ọwọ awọn ọmọ-ogun ti yoo lò wọn ni oju ogun ti a ṣe wọn fún. Bawo ni ọmọ-ogun ti kò gbé ihamọra wọ́ yoo ṣe le kọjuja si ẹni ti ó wọ ẹkunrẹrẹ ihamọra ogun? O sọ fun awọn Onigbagbọ́ wọnyii pe bi wọn yoo bá duro rara, yoo jẹ́ pe wọn ti gbé ihamọra wọ̀, ki wọn ba lè kọju ija si arekereke eṣu. Eṣu le tan ọkàn ti kò ni ifura jẹ ki o si bori rẹ̀ ni oriṣiriṣi ọna. O maa n wá pẹlu ọrọ didun ati ahọn ẹtan bi o ti jẹ si Efa ninu Ọgba Edẹni.

### Agbara Ọta

Agbara eṣu wà ni tootọ, o si banilẹru, ṣugbọn Ọlọrun ti fi aala silẹ fun ibi ti o le ṣe mọ. Olukuluku eniyan ni o ni ominira ti o si wà ni ipá rẹ̀ lati yàn lati kọju ija si agbara okunkun tabi ki o jẹ ki wọn bori oun. Nigba ti Ọlọrun ti pese ihamọra lati kọju ija si eṣu, O fun eniyan ni agbara iṣẹgun. Ija yii ki i ṣe pẹlu ọta ti a le fi oju ri, ṣugbọn pẹlu awọn ẹmi buburu oju ọrun ni. Oriṣiriṣi ilana ẹsin ti o sẹ́ Jesu bi Ọlọrun ati ọpọlọpọ ipilẹ ẹkọ Bibeli miiran, ni wọn ni ọmọ ẹyin pupọ. Awọn ilana wọnyii buru nitori pe eṣu fi wọn ṣe ohun elo lati da eto Ọlọrun fun igbala eniyan rú Iyàn-jija awọn onilana ẹsin wọnyii le fẹrẹ pa eniyan lọkan dà ki o si kún fun ọgbọ́n ẹ̀wẹ́, ṣugbọn sibẹ agbara eṣu ni. A kilọ fun awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun lati ṣọra pẹlu wọn ki wọn si gbé ihamọra Ọlọrun wọ́ ki wọn ba le kọju ija si arekereke eṣu.

### Ihamọra

Ihamọra Ọlọrun ni ọpọlọpọ ẹya, ṣugbọn a ṣakiyesi pe ekinni ti a gbani-niyanju lati tete gbé wọ̀ ni amure ọtitọ. Otitọ ni Ọrọ Ọlọrun, bi a ba si ti n fi Ọrọ yii di ọkàn wa ni amure ni a n gbaradi lati ja ija rere ti igbagbọ́. Igbàya ododo jẹ ẹri pe Otitọ ni wà ninu ọkàn. Jesu Kristi ni ododo wa, bi a ba si ti gbé Kristi wọ̀, a n ṣe ẹkọ Kristi lọṣọ. A n gbọran si I ati si Ọrọ Rẹ̀. Igbesi-ayé wa lode ara maa n tàn fun Kristi nitori pe Oun wà ninu ọkàn wa. A n fi imura Ihinrere wọ ẹsẹ̀ wa ni bata. A n ka Ọrọ Ọlọrun, a n gbadura, a n kẹkọọ, a si n tẹle Jesu loju ọna naa. A n mu ọkan wa wà ni imurasilẹ lati wá Oluwa nipa sisá fun ohunkohun ti o fara jọ ibi ati nipa yiyẹ ọkàn wa wò lojoojumọ. A ti kọ gbogbo ẹ̀ṣẹ ati ifẹkufẹ ayé silẹ lati tẹle E gẹgẹ bi Oluwa ati Ọga wa ni ọjọ ayé wa gbogbo. A darukọ apata igbagbọ́ gẹgẹ bi apa kan ihamọra naa, a si kọ́ wa ninu Bibeli pe “nipa gbigbọ ni igbagbọ́ ti iwá, ati gbigbọ nipa ọ̀rọ Ọlọrun” (Romu 10:17). Nitori idi eyi, pataki ju lọ ninu ihamọra wa ni Ọrọ Ọlorun. Bi eṣu ba le jà wá ni ole apakan ihamọra yii, gbogbo eyi ti o kù di asán.

A maa n pana gbogbo ọfa iná ẹni ibi ni nipa apata igbagbọ́. A ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun. A gba awọn ileri Rẹ̀ gbọ́, a si duro ti Ọrọ Rẹ̀. Igbagbọ́ a maa gba awọn nnkan ti Ọlọrun ṣe ileri bi ẹni pe O ti ṣe wọn. Kò yanilẹnu nigba naa lati pe e ni apata igbagbọ́. Bibeli yoo jẹ́ oku iwe lasan bi kò ba si igbagbọ́. A ni igbagbọ́ ninu Bibeli; a n pe e ni Iwe Ọlọrun. Nipa igbagbọ ni a mọ̀ pe a dá ayé nipa Ọrọ Ọlọrun. A n dá wa lare nipa igbagbọ. A maa n wà lai lẹbi niwaju Ọlọrun nipa igbagbọ ninu Ẹjẹ ti Jesu ta silẹ. Bi eṣu ba le jà wa ni ole igbagbọ́ a o maa ṣiyemeji ohun gbogbo, gbogbo ireti yoo si fò lọ. Ṣugbọn niwọn-igba ti a ba n rin ninu imọlẹ ti a si fi ara wa si ipò ti a o fi le duro pẹlu igbagbọ́ lori gbogbo ileri Ọlọrun, a ki yoo mọ iṣubu laelae.

Idalare nipa igbagbọ wà ninu ihamọra ti Ọlọrun ti pese fun wa. Iṣẹ oore-ọfẹ keji ti o daju ti i ṣe isọdimimọ ti i maa ṣẹlẹ ninu ọkàn wà ninu rẹ̀ pẹlu. Ileri Baba wà ninu rẹ̀ eyi ti i ṣe Olutunu, ani ifi Ẹmi Mimọ wọ ọkàn ti a sọdimimọ patapata. Jesu sọ fun awọn Onigbagbọ iṣaaju pe ki wọn má ṣe kuro ni Jerusalẹmu titi a o fi fi agbara wọ̀ wọn lati Oke wá. Wọ́n gbọran, wọn si n gbadura titi a fi rán Ẹmi Mimọ́ si wọn ni Ọjọ Pẹntikọsti. Wọn kò jade lọ ni aigbé gbogbo ihamọra wọ̀, ṣugbọn wọn duro lati ni edidi iriri Onigbagbọ́ yii ni igbesi-ayé wọn.

Onigbagbọ ti a ti fi ihamọra wọ̀ yoo mu Ida Ẹmi, ti i ṣe Ọrọ Ọlọrun, yoo si bẹrẹ si i jà. Ọta ni maa n ṣubu nigba ti a ba fi Ọrọ nì kò ó loju. Apẹẹrẹ rere fun eyi ni idanwo Jesu ninu aginju. Nigba ti Eṣu ba wá pẹlu idanwo kan, Jesu a dahun pe, “A ti kọwe rẹ̀.” A si fa gbolohun Ọrọ kan yọ ti o bá idanwo kọọkan mu. O si ṣẹgun Satani ni gbogbo igba, bẹẹ gan an ni a le ṣẹgun rẹ̀ lonii pẹlu bi a ba lo Ọrọ Ọlọrun, ti o yè ti o lagbara ti o si mú ju idakida oloju-meji lọ lati dojuja kọ ọ́.

### Adura

Adura jẹ́ pataki jù lọ ninu ihamọra Onigbagbọ. Lai si rẹ̀, gbogbo ẹya ti o kù di asán. Ọrọ Ọlọrun a maa di aaye nigba ti a ba fi awọn ileri Ọlọrun gbe e lẹsẹ nipa igbagbọ́. A maa n ni igbagbọ yii bi a ba ti n sun mọ Ọlọrun sii ninu adura ati Ọrọ Rẹ̀. Adura agbayọri maa n mi ọwọ Ọlọrun. Adura awọn eniyan Ọlọrun maa n bi agbara eṣu sẹyin. Nipa adura ni gbogbo isọji ati pipe Ẹmi Ọlọrun sọkalẹ sinu ọkàn awọn eniyan ti n wa. Apapọ awọn eniyan ti fohun-ṣọkan lati bẹbẹ niwaju Ọlọrun, wọn si bori. Isọji nla-nla ti dide nitori pe eniyan kan tabi apapọ awọn eniyan kan ti gbagbọ pe Ọõrun maa n duro ti ohun ti O sọ nigba ti O ṣe ileri lati gbọ́ adura.

### Ifẹ Ọkàn Paulu fun Adura

Paulu bẹ awọn Onigbagbọ ara Efesu wọnyii lati maa gbadura fun oun nigba gbogbo. O jẹ́ ikọ̀ ninu ide, ṣugbọn ifẹ ọkàn rẹ̀ ki i ṣe ominira nipa ti ara bi ko ṣe ominira ninu Ẹmi. O n fẹ ki wọn gbadura ki oun le ya ẹnu oun gbooro lati waasu Ihinrere kan naa nipa eyi ti o mu ki a fi i sinu tubu. O n fẹ lati ni igboya ti yoo mu ki iwaasu rẹ̀ le ni agbara lati pa awọn eniyan lọkan dà si otitọ Ihinrere. O sọ fun wọn pe ki wọn gbadura ninu Ẹmi. Eyi ṣe deedee pẹlu ekọ ati apẹẹrẹ ti Jesu pe, nigba gbogbo, adura wa gbọdọ jẹ gẹgẹ bi ifẹ Ọlọrun. Ni gbogbo igba ni o jẹ́ ifẹ Ọlọrun fun wa lati maa gbadura fun awọn wọnni ti wọn fi ayé wọn lelẹ lati waasu Ihinrere. Olukuluku Ajihinrere tootọ ni o maa n fẹ́ adura awọn eniyan Ọlọrun. Iranlọwọ nipa ohun ini ṣe danindanin ṣugbọn iwọnyi ki yoo le ṣe nnkan bi ko ṣe pe awọn eniyan Ọlọrun ba gbé iwuwo igbokegbodo iranṣẹ Ọlọrun naa lé ọkàn wọn ninu adura.

**Ihamọra fun Olukuluku**

Olukuluku ni o gbọdọ ṣe ara rẹ̀ yẹ fun ihamọra ti Ọlọrun ni fun un. A ki yoo beere lọwọ rẹ lati ṣe iṣẹ ti ẹlomiran ni lati ṣe. Ọlọrun ki yoo pè ọ lati ṣe ohunkohun ti o ju agbara rẹ lọ, ṣugbọn iwọ ni lati gbé ihamọra ni wọ̀ ti Ọlọrun ti pese ki iwọ ba le ṣe eyi ni ti i ṣe ojuṣe rẹ. Ni ọwọ́ ẹni ti a fun ni pupọ ni a o ti beere pupọ.

Nigba ti Dafidi n lọ lati lọ pade omiran nì, Goliati, o kọ̀ lati wọ̀ ihamọra Saulu Ọba. Saulu gbe e fun un, ṣugbọn nigba ti Dafidi wọ̀ ọ́ wò, o mọ pe oun kò le kọju ija si ọta Israẹli ninu irú ihamọra bẹẹ. Oun kò i ti dan an wò ri. Nitori eyi, o jade wa soju ija pẹlu kannakanna darandaran ati okuta didan marun-un. O sọ fun Goliati pe, “Iwọ mu idà, ati ọ̀kọ, ati awà tọ̀ mi wá; ṣugbọn emi tọ̀ ọ wá li Orukọ OLUWA awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun ogun Israẹli ti iwọ ti gàn” (1 Samuẹli 17:45). O jade wá lai si ihamọra ti ara, ṣugbọn ni orukọ Oluwa ati ninu ipá agbara Rẹ̀. Ọwọ kan ti a kò le fi oju ri ni o ṣe amọna okuta naa. Ọlọrun tọ́ ọ si ibi ti o yẹ ki o lọ --iwaju ori Goliati – bẹẹ ni Goliati ṣubu lulẹ ni okú.

Eniyan le fi oju inu wo ohun ti i bá ṣẹlẹ bi o ba ṣe pe o lọ ninu ihamọra ọba, ti o si gbẹkẹle agbara ti oun tikara rẹ̀. Ṣugbọn pẹlu igbẹkẹle rẹ̀ ninu Ọlọrun alaaye ati ihamọra ti a kòle fi oju ri ni ara rẹ̀, o ni iṣẹgun. O pa Goliati, a si mu ẹ̀gan si ogun Israẹli kuro. Awọn ti wọn bá fi igbẹkẹle wọn sinu Ọlọrun ki yoo mọ iṣubu laelae.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti a fi ni lati gbé gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀?
2. Ki ni awọn nnkan ti a n bá jijakadi ninu ogun ti ẹmi yii?
3. Ewo ni o le darukọ ninu ihamọra yii?
4. Nitori ki ni Paulu ṣe beere pe ki wọn maa ranti oun ninu adura?
5. Bawo ati igba meloo ni awọn eniyan mimọ́ ni lati maa gbadura?
6. Darukọ ọdọmọkunrin kan gẹgẹ bi apẹẹrẹ ti o yan ihamọra ti ẹmi dipo ti ara.